Claiming your Travel Costs if you are an Asylum Seeker: Yoruba



# Gbígba Àsanpadà Iye Owó Ìrìn-àjò rẹ bí o bá jẹ́ Ẹni tó sá wá láti Ìlú Òkèèrè láti wá Ààbò

Bí o bá jẹ́ Ẹni to sá wá láti Ìlú Òkèèrè láti wá Ààbò, bí a kò tilẹ̀ tíì gba ìwé tí o fi bèèrè fún èyí wọlé, o lè gba àsanpadà àwọn owó ìrìn-àjò rẹ láti ọ̀dọ̀ ilé-iṣẹ́ ìlera. Èyí túmọ̀ sí pé àwa yóò san àsanpadà owó tí o fi wọ bọ́ọ̀sì, ọkọ̀ ojú-irin tàbí owó epo tí o lò láti wá sílé ìwòsàn àti láti padà sílé.

Ìwé pélébé yìí ṣàlàyé ohun tí ìwọ yóò nílò láti gba àsanpadà iye owó ìrìn-àjò rẹ.

Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti gba àsanpadà àwọn owó tí o ná, lọ sí Ọ́fíìsì Akọ̀wé-owó. Ọ̀kan wà ní ilé-ìwòsàn. Bèèrè lọ́wọ́ òṣìṣẹ́ yòówù nipa bí o ṣe lè dé ibẹ̀ tàbí kí o fi ìwé pélébé yìí hàn wọ́n.

## Kíni mo lè gba àsanpadà fún?

**Bọ́ọ̀sì, ọkọ̀ ojú-irin, ọkọ̀ ojú-omi, abbl –** Jọ̀wọ́ fi àwọn tíkẹ́ẹ̀tì rẹ pamọ́, kí o sì kó wọn wá sí Ọ́fíìsì Akọ̀wé-owó

**Ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ –** A lè fún ọ ní iye tí o fi wá sílé ìwòsàn àti tí o fi padà sílé.

**Abánikiri –** Bí o bá nílò pé kí ẹnìkan bá ọ lọ síbití a ní kí o yọjú sí, abánikiri rẹ náà lè ní ẹ̀tọ́ láti gba iye owó ìrìn-àjò (jọ̀wọ́ bèèrè fún ìfọwọ́sí fún èyí lásìkò)

Ọ̀nà ìrìrìn-àjò tí owó rẹ̀ kéré jùlọ ni a lè sanwó fún. A kì yóò san àsanpadà fún iye owó taksi àfi bí dọ́kítà rẹ bá ti fọwọ́sí èyí tẹ́lẹ̀rí, bí àpẹrẹ, nítorí ìṣoro àti lè rìn.

## Kíni mo nílò láti mú wá?

Fún Akọ̀wé-owó láti san iye owó tí o ná, o gbọ́dọ̀ wá pẹ̀lú -

1. Káàdì Ìforúkọsílẹ̀ Ìkọ̀wé-bèèrè fún ààbò rẹ (ARC). Bí o kò bá tíì ní ọ̀kan, mú lẹ́tà tí a kọ sí ọ lẹ́yìn ìkọ̀wé-bèèrè rẹ dání.







2. Lẹ́tà tí a kọ láti fi sọ ọjọ́ tí ìwọ yóò wá tàbí Fọ́ọ̀mù Ìbéèrè Àsanpadà fún Owó Ìrìn-àjò fún Aláìsàn

3. Bí o bá fẹ́ gba owó fún bọ́ọ̀sì, ọkọ̀ ojú-irin, ọkọ̀ ojú-omi, abbl., kó àwọn tíkẹ́ẹ̀tì rẹ dàní wá.

**Nígbàtí o bá lọ sí Ọ́fíìsì Akọ̀wé-owó, o lè fi òdìkejì ìwé pélébé yìí hàn wọ́n, èyí tó ṣàlàyé ohun tó yẹ kí wọ́n ṣe láti fún ọ ní àwọn owó ìrìn-àjò rẹ.**



# Information for Cashier's Office

This leaflet has been produced specifically for asylum seekers wishing to claim travel expenses.

Asylum seekers, including failed applicants, qualify for reimbursement of travel expenses.

They must produce an Application Registration Card (ARC) as proof of their entitlement which details their name, date of birth and nationality as well as their photograph and fingerprints.







If this has not yet been issued they must present a time limited, standard acknowledgement letter which can be used until they receive an ARC.

Note that only asylum seekers are eligible - this does not apply to other types of application such as those made under Human Rights legislation.

It is unlikely that an asylum seeker will have access to a bank account so reimbursements should be made in cash.